## Awọn aami ati aami aarun

### Kọọli:

- iba
- Ori fifọ lile
- èébì
- ọrun gigan
- Ikorira awọn ina to mọlẹ
- ara susu
- iporuru, aimoye
- airoorun sun lile, ooyi
- giri

### Kokoro inu ẹjẹ:

- iba ati gbigbọn
- èébì
- awọn inira ati irora ẹsẹ ati orikerike ara lile
- ọwọ ati ẹsẹ to tutu gidigidi
- awọ ara funfun tabi hihunjọ
- mimi lokeloke
- igbẹ gbuuru ati imu kikan
- ara 'bibo' pipọn tabi ara susu pẹlu awọn oju ti kii parẹ labẹ ìkìmólë - njẹ ayẹwo gilasi naa ṣe afihan oju-ewe to kan. Lori awọ to dudu, yẹ inu ipenpeju tabi oke ẹnu wo nibiti oju rẹ ti le han kedere sii
- inira irin tabi idide duro
- airoorun sun lile, ooyi

**Kiiṣe gbogbo eniyan lo maa ni awọn aami aarun wọnyi - wọn le s'afihan ni lọnakọna ti o si dapọ laarin awọn ailera meji. O ṣe pataki lati wa imọran iṣegun ni kiakia bi iwọ tabi ọrẹ kan ba ni aami aarun ifoya tabi ipo kan to nburu gidigidi.**

**Rii daju wipe iwọ, idile rẹ ati awọn ọrẹ rẹ tọju ara yin ati wipe ẹnikan mọ ki ara rẹ ko ba ya ki wọn le tọju rẹ. Eyi le jẹ igbe-aye aabo!**

### Fun iwifun siwaju si kansi

**Ajọ Iwadii Kọọli**
Opo ipe ọfẹẹ 0808 80 03 344
**www.meningitis.org**

**Kọọli Nisisiyi**
opo ipe wakati 24
0808 80 10 388
**www.meningitisnow.org**

**Awọn opo to wulo:**

- www.nhs.uk/conditions/meningitis
- www.nhs.uk/vaccinations
- www.nhs.uk/conditions/vaccinations/men-acwy-vaccine

UK Health Security Agency

NHS

© Crown copyright 2023
Product code IM23DISL1YO Yoruba. 1P 30k AUG 2023 (APS).
UK Health Security Agency gateway number: 2023-391

Iwe pelebe yii wa larọwọto bii braille, Easy Read, ọrọ to rọrun, ohun, fidio BSL ti a si tumọsi awọn ede 28. Jọwọ ṣe abẹwo si **www.healthpublications.gov.uk** lati beere fun awọn ẹda tirẹ loni tabi pe 0300 123 1002

UK Health Security Agency

NHS

# Kọọli ati aarun inu ẹjẹ

## Maṣe kọti ikún si awọn aamin naa




immunisation
the safest way to protect your health

## Mọ, mura

Kọọli Meningococcal (Wiwu itẹnu ọpọlọ ati opo ẹyin) ati kokoro inu ẹjẹ (majele ẹjẹ) ko wọpọ sugbọn awọn aarun lile to le pani tabi fa awọn isoro ailera ati ilera sinu aye eniyan. Kọọli ati kokoro inu ẹjẹ le yọri si sepsis.

**Awọn agunbanirọ, ati akẹkọ fasiti paapaa, wa ni ewu giga**. Sugbọn o le daabobo ara rẹ tako iru aarun meningococcal mẹrin nipa gbigba abẹrẹ ajẹsara MenACWY ọfẹẹ.

## Daabobo ara rẹ pẹlu abẹrẹ ajẹsara MenACWY

Ọpọ awọn agunbanirọ orilẹ-ede UK ati awọn ọdọ agba lati Ọsu Kẹsan 1996 ko ba ti gba abẹrẹ ajẹsara nigbati wọn ni ile-ẹkọ sugbọn wọn yege titi wọn yoo fi ṣe ọjọ-ibi 25. Awọn akẹkọ okere to nwọ fasiti UK fun igba akọkọ ti wọn ko tii gba abẹrẹ ajẹsara MenACWY naa yege titi wọn yoo fi ṣe ọjọ-ibi 25 wọn. Bi o ba yẹ ninu ẹgbẹ wọnyi ti o ko tii gba iwe abẹrẹ ajẹsara naa ni ipade pẹlu GP rẹ nisisinyi. Bi ko ba da ọ loju jiroro eyi pẹlu GP rẹ.

Abẹrẹ MenACWY munadoko lati dena aarun kọọli meningococcal ati kokoro inu ẹjẹ ti MenA, MenC, MenW ati MenY nfa.

Sugbọn ranti wipe eyi **abẹrẹ ajẹsara ko le dena gbogbo iru aarun kọọli ati kokoro inu ẹjẹ**. Nitorinaa o ṣe pataki wipe o mọ nipa awọn aami ati aami aarun naa.

**Ṣe ayẹwo loorekoore lori ẹnikẹni ti ara rẹ ko ba ya, o le daabobo aye kan**

**Mọ awọn aami ati aami aarun kọọli ati kokoro inu ẹjẹ**





### Ayẹwo gilasi

Tẹ ẹgbẹ gilasi imumi mọ tako ara sisu ki o si wo boya ara sisu naa to parẹ ti o si padanu awọ labẹ idamu. Bi ko ba parẹ, gba iranlọwọ itọju iṣegun lẹsẹkẹsẹ. Bi ara rẹ ko ba ya, gba iranlọwọ bakanbakan, koda bi ara susu naa ba parẹ tabi ko ba han rara.

## Kini awọn aami ati aami aarun?

Ọpọ awọn aami isaaju - eebi, iba, irora, rirẹ ati ori fifọ - tun ni awọn aami ailera ti ko le ju bii otutu ati ọfinkin. Sugbọn ẹnikan pẹlu kọọli tabi kokoro inu ẹjẹ yoo saaba jẹ aisan to le laarin wakati diẹ.

Eyi ni idi ti o fi ṣe pataki lati ma yẹ ẹlomiran ti ara rẹ ko ya wo lati mọ boya o nburu si fun wọn kiakia ati lati maa wa awọn aami ati aami aarun. Tete wa iranlọwọ iṣegun bi o ba ni ifoya nipa ilera wọn tabi tirẹ.

O ṣe pataki bakannaa lati maa wa ọwọ ati ẹsẹ tutu, irora ẹsẹ lile ati awọ ara pipọn, gẹgẹbi eyi ti le yọri si aisan. Awọn aami aarun bii ara susu ti ko le parẹ (ṣe ayẹwo gilasi s'afihan odi), piporuru ọkan tabi aimoye, tabi oorun asunju lati ji le pupọ.

## Bawo ni kọọli ṣe nran?

Kokoro aarun to nfa awọn aarun wọnyi ma nsaba ran nipa ifarakinra pẹki-pẹki tabi jinna sira. Ọpọ awọn nkan wọnyi iṣẹlẹ lọkọọkan sugbọn fọn jade nigba miiran ni ile-ẹkọ tabi nibiti awọn eniyan ti npin aaye, bii gbọngan fasiti.

**Gba abẹrẹ ajẹsara MenACWY rẹ ni ọdọ GP rẹ. Ni awọn agbegbe kọọkan o le wa larọwọto ile ita oogun.**